COVID-19 VACCINE
Public Health Advice



# Abẹ́rẹ́-àjẹsára COVID-19

## Abẹ́rẹ́-àjẹsára fún COVID-19; Àlàyé Pataki nìpa abẹrẹ-àjẹsára Pfizer/BioNTech, Comirnaty

Ẹ̀ dà 5

Ọjọ́ Kẹwàá Oṣù Kejì Ọdun 2021

Rialtas na hÉireann
Government of Ireland

## Nipa ìwé pélébé yii

Ìwé pélébé yii sọ n fun ọ nipa abẹ́ rẹ́ -àjẹsára COVID-19 (fairọọsi korona).

Ó n ´sọ fun ọ nipa:

- kini COVID-19jẹ
- kiniabẹ́rẹ́-àjẹsára COVID-19jẹ
- tani yíò kọkọ́ gbà àti kíni èrèdí
- iditi oṣe ṣe patakilatigbaabẹ́rẹ́-àjẹsára naa
- tani kò yẹ kó gba a ati tani o yẹ kí ó ma ti i gbaa
- aabo gbigba abẹ́ rẹ́ -àjẹsára ati awọn iṣẹ́ òdìrẹ̀
- ibiti o ti le gba alaye siwaju sii

Jọwọ ka ìwé pélébé yii daradara. O tun le bá onímọ̀ isẹ-ilera kan sọrọ, bii GP (Dọkítà) tabi Apòògùn rẹ nipa abẹ́ rẹ́ -àjẹsára naa.

## Kini COVID-19?

**COVID-19 jẹ aisan kan tí ó lè ṣe àkóbá fún awọn ẹdọforo ati gògòńgò rẹ, ati nigba miran sí awọn ẹya ara rẹ miran. Fairọọsi kan tó n jẹ korona-fairọọsi ló n fà á. COVID-19 maa n yára tankalẹ gan an.**

Ó maa n tankalẹ ninu afẹfẹ nipasẹ awọn oje-ara nigbati awọn eniyan bá húkọ́ tabi sín, tabi nigbati wọn ba fọwọkan awọn ibi ti awọn oje-ara naa balẹ̀ sí, tí wọn sì fi ọwọ wọn naa ba oju, imu tabi ẹnu wọn.

COVID-19 n fa aisan tó le gan an, dá eiyan dubulẹ ní ile-iwosan, tabi kí o yọrisi iku.

**Awọn imọlaara aiṣan COVID-19 tí ó wọ́pọ̀ ni:**

- iba (ara gbigbona tí ó tó 38oC tabi ju bẹẹlọ)
- irufẹ ikọ tuntun kan – eyi lè jẹ ikọ eyikeyi, ki i kan ṣe ikọ egbẹlasan
- èémí kúkúrú tabi iṣoro mímíèémí
- àìlè gbọ òórùn tabi kí ayipada bá gbígbọ́ òórùn tabi ìtọ́ wò – eyi tumọ si pe o kò lè gbọ òórùn tabi mọ adùn ohunkohun tabi kí òórùn tabi ìtọ́ wò gbogbo nnkan ma yatọ sí arawọn

O le ma ni gbogbo awọn ìmọ̀lára àìsàn yii tabi kí ara rẹ maṣe deede. Ó le to ọjọ mẹrinla kí awọn ìmọ̀lára àìsàn naa tó farahan. Wọn sì le farajọ iru awọn ìmọ̀lára àìsàn otutu tabi ibà.

Tí ò bà nì eyikeyi awọn ìmọ̀lára àìsàn COVID-19 tí ó wọpọ naa, ya ararẹ (maṣe kuro ninu yara rẹ), kí o sì pe GP (Dọkítà) kan lori foonu. Wọn le ṣeto ayẹwo COVID-19 fun ọ. Fun alaye siwaju si i lori COVID-19, jọwọ ṣabẹwo si **www.HSE.ie/coronavirus** tabi pe HSELive lori foonu **1850 24 1850.**

## Awọn wo ní n bẹ ninu ewu COVID-19 julọ?

Awọn eniyan tí ọjọ-ori wọn jẹ́ marundilaadọrin (65) ati ju bẹẹ lọ, pẹlu awọn tí wọn ní awọn ipo ailera kan nbẹ ninu ewu to ga julọ nigbati aisan COVID-19 bá kọlu wọn.

Awọn arugbo tí n gbe ni awọn ile-iṣẹ itọju onígbà pipẹ ní ewu ṣiṣe aisan tó lagbara nigba ti wọn bá ní aisan COVID-19, nitori tí fairọọsi naa maa n yára tàn kiri laarin awọn eniyan ti n gbe papọ.

Awọn oṣiṣẹ ilera pẹlu n bẹ ninu ewu tí ó ga pupọ ju awọn ẹlomiran lọ nigba tí wọn bá fi ara kó aisan COVID-19.

## Kini abẹ́rẹ́-àjẹsára COVID-19?

Abẹ́rẹ́-àjẹsára jẹ nnkan tí ó yẹ kí ó fun ara ní àjẹsára (idaabobo) kuro lọwọ aisan kan pato.

Abẹ́rẹ́ -àjẹsára COVID-19 yoo fun ọ ni aabo kuro lọwọ COVID-19.

Ti awọn eniyan ba gba abẹ́rẹ́-àjẹsára, o yẹ kì ó tùn mú àdínkù bá iye awọn tí o n ṣaisan naa tabi paapaa iye awọn tí COVID-19 le ṣe iku pa ní agbegbe wa. Awọn abẹ́rẹ́-àjẹsára n kọ awọn ọlọpaa agọ ara rẹ bí wọn ṣe lè daabobo ọ lọwọ awọn aisan.

Ó dára pupọ kí awọn ọlọpaa agọ ara rẹ kẹkọọ bí wọn ṣe lè daabobo ọ nipasẹ abẹ́rẹ́-àjẹsára ju kí o kó aisan COVID-19 lọ.

## Tani yíò kọkọ́ gba àti kíni èrèdí?

Awa (Aláṣẹ Iṣẹ Ilera) yoo kọkọ fun awọn eniyan tí n bẹ ninu ewu COVID-19 julọ ní abẹ́rẹ́-àjẹsára naa.

A óò máa fún ni ní àbẹ́rẹ́ àjẹsára náà bí ó bá ti ń dé ìlú Ireland.

O lè rí àtẹ àwọn onírúurú ẹgbẹ́ tí ó wà fún àbẹ́rẹ́ àjẹsára lórí ojú ewé ayélujára: **www.gov.ie/covid19vaccine**

**Nigba ti ó jẹ pe o kù sí ọ lọwọ lati pinnu gbigba abẹ́rẹ́-àjẹsára naa, HSE gba ọ niyanju pé kí o ṣe bẹẹ ni kete ti a ba fifun ọ. Ọ̀ fẹ́ ni HSE n funni ní abẹ́rẹ́-àjẹsára yii.**

O nilo lati ka iwe pelebe yii ati Iwe pelebe Àlàyé Aláìsàn ṣaaju ki o to gba abẹ́ rẹ́ -àjẹsára naa. O le rí Iwe pelebe Àlàyé Aláìsàn lori **www.hse.ie/covid19vaccinePIL.** O tun le ba onímọ̀ ilera kan sọrọ kí o tó gbà á. Tí o bá pinnu lati gba abẹ́ rẹ́ -àjẹsára naa, iwọ yoo fun wa ní iyọ-nda rẹ, eyi tí a maa ṣe akọsilẹ rẹ̀ .

## Tani alábẹ́rẹ́-àjẹsára mi?

Alábẹ́rẹ́-àjẹsára rẹ ni ẹniti yoo fun ọ ni abẹ́rẹ́-àjẹsára rẹ. Wọn jẹ akọṣẹmọṣẹ o ṣiṣẹ ilera tí ó n ṣiṣẹ pẹlu HSE, bi i Nọọsi, Dokita tabi Apòògùn

## Kini idi ti o ṣe ṣe pataki lati gba abẹ́rẹ́-àjẹsára COVID-19?

Gbigba abẹ́ rẹ́ -àjẹsára COVID-19 yẹ ki o daabobo ọ kuro lọwọ awọn àkóbá COVID-19. Erongba wa nipa fifun awọn eniyan ní abẹ́ rẹ́ -àjẹsára naa ni lati daabobo awọn eniyan ati lati ṣe àdínkù aisan ati iku tí fairọọsi yii n fà.

## Mo ti ni COVID-19 tẹlẹ, nitorinaa se mo tún nilo lati gba abẹ́rẹ́-àjẹsára naa?

Bẹẹ ni. Biope o ti ní COVID-19 tẹlẹ, o tún le pada wa ṣe ẹ.

Abẹ́rẹ́-àjẹsára naa yoo ṣe adinku ewu rẹ lati gba COVID-19 lẹẹkansii. Paapa ti o ba gba COVID-19 lẹẹkansii, abẹ́rẹ́-àjẹsára naa le ṣe àdínkù bí awọn ìmọ̀lára àìsàn naa yoo ṣe rí ní àgọ̀ ara rẹ

## Mo ni COVID-19 bayii, ṣe ó yẹ ki n tún gba abẹ́rẹ́-àjẹsára naa?

Rara. O yẹ ki o mára dúró fún gbigba abẹ́ rẹ́ -àjẹsára naa titi iwọ yoo fi bọ́ lọwọ COVID-19

**Ṣe eyi fun:**

- o kere ju ọsẹ mẹrin lẹyin ti o kọkọ ṣe akiyesi awọn ìmọ̀ lára àìsàntabi
- ọsẹ mẹrin lati igba tí ayẹwo sọ pe o ti ní aisan COVID-19

# Gbigba abẹ́rẹ́-àjẹsára naa

### Níbo ni mo ti lè gba abẹrẹ̀ àjẹsára náà?

A óò fún ọ ní abẹ́rẹ́ àjẹsára náà ní àgọ́ ìwòsàn tí wọ́n ti ń gba abẹ́rẹ́ àjẹsára, ní ọdọ Oníṣègùn òyìnbó rẹ, tàbí ní ilé ìtajà egbògi òyìnbó.

Bí o bá ń gbé ní ilé-ìtọ́jú onígbà pípẹ́, a óò fún ọ ní abẹ́rẹ́ àjẹsára náà ní ilé ìtọjú náà.

Bí o ba jẹ òṣìṣẹ́ ìlera tí ń ṣiṣẹ́ tààrà pẹlú àwọn tí o lè ní àìsàn COVID-19, a óò fún ọ ni abẹ́rẹ́ àjẹsára náà ní ibi tí o ti ń ṣiṣẹ́ tabi ní àgọ́ ìwòsàn tí wọn ti ń gba abẹrẹ́ àjẹsára.

Nígbà tí ó bá tó àkókò tìrẹ, a óò jẹ́ kí o mọ̀bí o ṣe lè gba tìrẹ nipasẹ ìpolongo tàbí kí a ránṣẹ́ sí ọ tààrà. O ṣe pataki lati maṣe kan si HSE fun abẹ́ rẹ́ -àjẹsára ṣaaju àkókònaa.

## Kini abẹ́rẹ́-àjẹsára wa?

Abẹ́rẹ́-àjẹsára ti a nsọ ni a pe ni Comirnaty, tí Pfizer/BioNTech ṣe.

Abẹ́rẹ́-àjẹsára mRNA yii nkọ ara rẹ bi o ṣe le peṣe proteini ti yoo mú kí ara kọ aisan naa, lai gba COVID-19 láàyè lati ṣe ohunkohun.

Lẹhinna ni ara rẹ yoo gbé awọn ọlọpaa-ara tí yoo ṣeranwọ lati bá aisan naa jà dide nigbati fairọọsi COVID-19 bá kuku wọnu ara rẹ ni ọjọ iwaju.

## Bawo ni a ṣe n gún abẹ́rẹ́-àjẹsára COVID-19 naa?

Abẹ́ rẹ́ -àjẹsára COVID-19 ni a maa n gún bí abẹrẹ ní òkè apa rẹ. Yoo gba tó iṣẹju diẹ.




## Gígún ẹẹmelo ni abẹ́rẹ́-àjẹsár aCOVID-19 tí mo nilo?

Iwọ yoo nilo gígún ẹẹmeji abẹ́rẹ́-àjẹsára COVID-19 lati ni aabo to daju julọ. O nilo lati gba ẹlẹẹkeji ní ọjọ mejidinlọgbọn (28) (ọsẹ mẹrin geere) lẹyin gbigba ti akọkọ.

## Ṣe abẹ́rẹ́-àjẹsára naa jẹ ailewu?

Ìgbakigba tí HSE bá kún ojú-òsùnwọ̀ n kò-séwu ati imunadoko nìkan ni wọn maa n gún abẹ́ rẹ́ -àjẹsára naa.

Bí iṣẹ ṣiṣe agbejade abẹ́rẹ́-àjẹsára COVID-19 ti yara gberu pupọ ju bí a ṣe lero lọ, abẹ́rẹ́-àjẹsára naa ti a nfun ọ yii ti pegedé gbogbo awọn igbesẹ tó yẹ fún agbejade rẹ̀ ati gbigba aṣẹ pé kò léwu, tí ó sì munadoko.

Lati le jẹ ki o gba àṣẹ fun lilo, abẹ́rẹ́-àjẹsára COVID-19 yii ti pegedé lori gbogbo awọn iwadii ilera ati awọn ayẹwo kò-séwu tí gbogbo awọn oogun miran tó ti gba aṣẹ la kọja, nipa titẹle awọn iṣedeede kò-séwu tiagbaye.

Abẹ́rẹ́-àjẹsá ra naa ti a fun ọ ni a pe ni Comirnaty, ti Pfizer/BioNTech ṣe:

- ✔ a ti dan an wo lára ẹgbẹẹgbẹrun eniyan gẹgẹ bi apakan ninu awọn iwadii ilera
- ✔ ó ti pegedé kíkún ojú-òsùnwọ̀ n kò-séwu, dídára ati mimunadoko, ó sì ti gba iwe-aṣẹ lati ọdọ awọn olóòtú. Fun orilẹ-ede Ireland, olóòtú ibẹ ni Ile-iṣẹ Oogun Ilẹ Yuroopu (EMA) - ṣabẹwo sí www.ema.europa.eu fun alaye siwaju

## Kini awọn ișẹ́ òdì abẹ́rẹ́-àjẹsára naa?

Bi i gbogbo awọn oogun, abẹ́rẹ́-àjẹsára le ṣiṣẹ́ òdì ninu ara. Pupọ ninu iwọnyi lè jẹ́ fẹ́ẹ́rẹ́fẹ́ tabi iwọnba ninu ara, fun igba diẹ, ati pe ki i ṣe gbogbo eniyan ní ó maa n rí bẹẹ fún.

Ó lé ní ọkan ninu eniyan mẹwaa tí wọn le ní ìrírí bí i:

- ríreara
- ojú ibiti wọn ti gba abẹ́rẹ́-àjẹsára naa sí apá wọn yoo dẹ̀, yoo wú tabi kí ibẹ̀ pọ́n roro
- ẹfọri
- ìrora inuẹran-ara
- ìròra oríkèèríkèéara
- ọkànrírìn
- àìsàn ibà (ìmóoru bí i 38ºC tabi ju bẹẹlọ)

Ni awọn igba tí kò wọpọ, ojú ibiti a ti gún abẹ́ rẹ́ -àjẹsára naa maa n yún awọn, awọn iṣan keekeke a maa wú, tabi ki wọn ma rí oorun sùn. Awọn ișẹ́ òdì yii ni a ri lara o lé ni ọkan nínú ẹgbẹrun kan eniyan. Arun Bell's palsy jẹ isẹ́ òdì kan ti kò wọpọ, tí a ti rí lara diẹ lé ju ọ̀ kan ninu ẹgbẹrun mẹwaaeniyan.

Àwọn àbẹyìnyọ tí ó lòdì, bíi gbígbòdì egbògi lára tí ó lágbára, kò wọpọ̀ rárá, a máa wáyé lára ènìyàn kan ṣoṣo ní ààrín ọ̀kẹ́ márùn ún ènìyàn. Alábẹ́rẹ́-àjẹsára rẹ lóye ṣiṣe itọju ailera kan tí o lé nitori abẹ́rẹ́-àjẹsára naa kò báara dọ́ gba.

Abẹ́rẹ́-àjẹsára COVID-19 ti pegedé lori gbogbo awọn iwadii ilera ati awọn ayẹwo kò-séwu tí gbogbo awọn oogun miran tó ti gba aṣẹ la kọja, tí alaye lori awọn ișẹ́ òdì ọlọ́ jọ́ pípẹ́ nipa eyi kò sìwọpọ.

Bi awọn eniyan diẹ si i ni orilẹ-ede Ireland ati ní agbaye bá ṣe n gba abẹ́ rẹ́ -àjẹsára yii, ẹkunrẹrẹ alaye lori awọn ișẹ́ òdì yii lè maa yọju.

HSE yoo maa ṣe afikun awọn alaye yii nigbagbogbo lori oju opo ayelujara wa, ati pe tí ó bá sì jẹ́ dandan, yoo ṣe afikun awọn alaye inu iwe pelebe ti a fun awọn eniyan ni akoko gbigba abẹ́ rẹ́ -àjẹsára akọkọ tabi ẹẹkeji

## Ibá lẹ́yìn abẹ́rẹ́-àjẹsára

O wọpọ pupọ lati ní àìsàn ibà lẹyin gbígba abẹ́rẹ́-àjẹsára. Nigbagbogbo, eyi n ṣẹlẹ laarin ọjọ meji (wakati 48) ti o gba abẹ́rẹ́-àjẹsára naa, ó sì maa n lọ laarin ọjọ meji.

O ṣee ṣe ki o ní ibà lẹyin gbígba abẹ́rẹ́-àjẹsára ẹlẹẹkeji rẹ. Tí ara rẹ kò bá balẹ̀, mu paracetamol tabi ibuprofen bí wọn ti ṣe juwe rẹ̀ lára paali tabi lori iwe pelebe naa.

Tí ọkàn rẹ kò bá balẹ̀, jọwọ lọ gba imọran lọwọ dokita.

## Nję abéré-àjęsára COVID-19 le fun ọ ni COVID-19?

Rara. Abéré -àjęsára COVID-19 ko le fun ọ ni COVID-19.

O şee şe kí o ti kó COVID-19 şaaju ki o to gba abéré-àjęsára rę, kí o sì ma mọ pe o ni awọn ìmọ̀lára àìsàn naa titi di akoko ipinnu gbígba ajęsara rę.

Ti o ba ni awọn ìmọ̀lára COVID-19 naa tó wọpọ, o şe pataki lati ya ararę sọtọ (maşe kuro ninu yara rę), kí o sì şeto ayęwo ọfę lati mọ daju boya o ti ní COVID-19.

Ti o ba ni aisan ibà tó bęrę ju ọjọ meji lọ lęyin tí o gba abé ré -àjęsára, tabi tí ó ju ọjọ meji lọ, o yę ki o ya ararę sọtọ, kí o sì beere lọwọ GP lati şeto àyẹ̀wò COVID-19 fun ọ.

Tí o bá ni awọn ìmọ̀lára àìsàn lęhin gbígba abéré-àjęsára akọkọ, o tun maa nilo lati gba ęlęękeji. Bí o ti jé pé abé ré -àjęsára akọkọ yoo daabo dię bò ọ, gbígba ęlęękeji yoo fun ọ ni aabo to nípọn julọ lọwọ fairọọsi naa.

## Nję awọn eniyan kan nbę ti ko yę ki wọn gba abéré-àjęsára COVID-19?

**Bęę ni. O kò gbọdọ gba abéré-àjęsára COVID-19 tí ó bá jé pé:**

- ✗ eyikeyi ninu awọn eroja inu abéré-àjęsára naa kò bá ara rę dógba rara nigba kan rí (pęlu polyethylene glycol). Ka Iwe pelebe Àlàyé Alaisan lati wo orukọ awọn eroja naa.
- ✗ abéré-àjęsára akọkọ kò bá ara rę dó gba rara.

Bí abéré-àjęsára kan tàbí ìtọjú alabęrę yòówù, tàbí polysorbate 80 bá ti gbòdì lára rę rí, o nilati bá dọkítà rę sọ̀rọ̀kí o tó gba abéré-àjęsára COVID-19.

Ọpọlọpọ eniyan yoo ni anfani lati gba abéré-àjęsára naa lailewu. Ęni ti o fun ọ ni abéré-àjęsára yoo fi tayọtayọ dahun ibeere yoowu tí o ní nigba ti a fun ọ lati gba abéré-àjęsára naa.

Wọn yoo tun fun ọ ni iwe pelebe imọran lęyin itọju, ati kaadi akọsilę abéré-àjęsára kan tó n şafihan orukọ ati nọmba ìdì abéré-àjęsára naa ti a fun ọ.

## Şe mo lè gba abéré-àjęsára COVID-19 ti mo bá ní ara gbigbona?

Rara. O nilati ni suuru fún gbigba abéré-àjęsára naa ti o bani ibà (ara gbigbona 38oC tabi ju bęę lọ), titi ararę yoo yá.

## Şe kò léwu lati gba abéré-àjęsára tí eniyan bá loyun tabi n fun ọmọ lọ́mú?

Ko si àrídájú kankan pe abéré-àjęsára COVID-19 léwu fun alaboyun.

A kò dán abẹ́rẹ́-àjẹsára yii wò daadaa lara awọn alaboyun nitorinaa ìwọ̀nba ni àrídájú tó wà ní akoko yii.

Ti o ba jẹ oṣiṣẹ ilera kan tabi jẹ́ ọ̀kan lara ẹgbẹ́ kan tí nbẹ ninu ewu, tí o sì loyun, o yẹ kí o bá dokita oyún rẹ tabi GP sọrọ nipa gbigba abẹ́rẹ́-àjẹsára COVID-19. O lè gba abẹ́rẹ́-àjẹsára COVID-19 tí o bá n fun ọmọ lọ́ mú.

## Ó maa tó àkókò wo kí abẹ́rẹ́-àjẹsára tó bẹrẹ ṣiṣẹ?

Lẹyin abẹ́rẹ́-àjẹsára COVID-19 mejeeji, ọpọlọpọ eniyan yoo ni àjẹsára. Eyi tumọ si pe wọn yoo ni aabo lodi si COVID-19.

Yoo gba tó ọjọ 7 lẹyin ti o gba ẹlẹẹkeji kí ó tó maa ṣiṣẹ.

Àyè sì wà pé o tún lè ní COVID-19, koda kí o ti gba tẹlẹ naa.

## Njẹ abẹ́ rẹ́-àjẹsára naa n ṣiṣẹ fun gbogbo eniyan?

A ti dán abẹ́rẹ́-àjẹsára naa wò lara awọn eniyan tó jẹ ọmọ-ọdun mẹrindinlogun (16) ati jubẹẹ lọ. Àrídájú tí n bẹ lọwọlọwọ ni pé abẹ́rẹ́-àjẹsára n daabobo eniyan tó iwọn 95%.

Tí agọ-ara rẹ kò bá dápé daadaa, ko si ewu Kankan nipa gbigba abẹ́rẹ́-àjẹsára naa ṣugbọn o lè ma ṣiṣẹ tò lara rẹ.

## Bawo ni mo ṣe fẹ́ jábọ̀ awọn iṣẹ́ òdì naa?

Bó ṣe wà pẹlu gbogbo awọn abẹ́ rẹ́-àjẹsára, o lè jábọ̀ awọn iṣẹ́ òdì tí o furasí fún Ile-iṣẹ Iṣakoso Awọn Ọja Ilera (HPRA).

HPRA ni alaṣẹ ní orilẹ-ede Ireland fun awọn oogun, awọn ẹrọ itọju ati awọn ọja ilera miiran.

Gẹgẹbi apakan ninu ipá rẹ fun fífojúsí ailewu oogun, HPRA ní agbekalẹ kan eyiti awọn oṣiṣẹ ilera tabi ara ilu lè jàbọ́ awọn iṣẹ́ òdì yoowu tí wọn fura sí, tí ó ní nnkan ṣe pẹlu awọn oogun ati awọn abẹ́ rẹ́ -àjẹsára bí o ti n ṣẹlẹ ni orilẹ-ede Ireland.

HPRA gbani niyanju pé kí a fun wọn ní iroyin awọn iṣẹ́ òdì tí a bá fura sí, eyiti o ni i ṣe pẹlu awọn abẹ́ rẹ́-àjẹsára COVID-19 lati lè ṣatilẹyin fifojúsí ní lemọlemọ sí lílò wọn ní ailewu ati mimunadoko wọn.

Lati jabọ awọn iṣẹ́ òdì tí a bá fura sí pe abẹ́ rẹ́ -àjẹsára COVID-19 n fà, jọwọ ṣabẹwo sí www.hpra.ie/report.

O tun le beere lọwọ Dokita rẹ tabi mọlẹbi kan lati bá ọ jabọ eyi. Gbogbo alaye tí ó bá n bẹ ni ki wọn sọ jade, ati tí o bá ṣee ṣe, kí wọn pese nọmba ìdì abẹ́rẹ́-àjẹsárapẹlu.

HPRA ko le pese imọran iwosan lori awọn ọrọ kọọkan. Awọn ara ilu yẹ ki wọn kàn sí akọṣẹmọṣẹ ilera wọn (Dokita wọn tabi Oniwosan) pẹlu awọn ifiyesi iṣoogun eyikeyi ti wọn le ni.

## Di igba wo ni abẹ́rẹ́-àjẹsára maa n ṣiṣẹ lára dà?

Ní lọwọlọwọ yii, a ko tí ì mọ igba tí abẹ́rẹ́-àjẹsára maa ṣiṣẹ tó. Awọn àgbeyẹ̀wò ilera nlọ lọwọ lati mọ eyi.

## Nigbati mo ba gba abẹ́rẹ́-àjẹsára naa, ṣe eyi tumọ pe emi kò lè kó COVID-19 ràn awọn ẹlomiran niyi?

A ko tì í mọ boya gbigba abẹ́ rẹ́-àjẹsára naa kò ní í lè jẹ́ kí ẹnikan kò COVID-19 ràn awọn ẹlomiran. Idi niyi tí o fi ṣe pataki ki gbogbo wa tubọ maa tẹle imọran ilera lawujọ lati lè dẹkun itankalẹ fairọọsi naa. Paapa julọ, o tun nilo lati:

- tẹle awọn itọnisọna títakété si ẹnikeji lawujọ (fi mita meji silẹ sí ẹlomiran ni awọn ibiti o ti ṣee ṣe)
- wọ ibojubonu
- fọ ọwọ́ rẹ déédéé

**HSE, Ẹka Ètò Ilera ati Ajọ Agbaye fun Ilera gbani niyanju pé kí awọn eniyan gba abẹ́rẹ́-àjẹsára COVID-19 nigbati wọn ba filọ̀ wọn.**

**A dupẹ pe o n daabobo ararẹ ati awọn ẹlomiran**

## Alaye siwaju si i

Fun alaye siwaju si i, ka Iwe pelebe Àlàyé Alaisan. Wọn maa tẹ eyi jade fun ọ ni ọjọ tí o ba gba abẹ́rẹ́-àjẹsára rẹ,tabi o le rí Iwe pelebe Alaye Alaisan naa lori **www.hse.ie/covid19vaccinePIL**

O tun le ba akọṣẹmọṣẹ ilera bi i GP (Dọkítà), Apòògùn rẹ tabi ikọ̀ ilera sọrọ.

O tun le ṣabẹwo si oju opo ayelujara HSE tí n bẹ ní **www.hse.ie/covid19vaccine** , tabi kí o pè HSELive lori **1850 24 1850.**

Fun alaye siwaju si i lori abẹ́rẹ́-àjẹsára COVID-19, pẹlu awọn ohun elo miran fun kíkà ati ní awọn èdè miran, ṣabẹwo sí **HSE.ie/covid19vaccinematerials**

# Alaye ararẹ

Lati le funni ní abẹ́rẹ́-àjẹsára laisewu ati lati ṣe akọsilẹ gbogbo alaye pataki fun amojuto ati ṣiṣakoso abẹ́rẹ́-àjẹsára naa, HSE yoo ṣètò awọn alaye nipa ararẹ.

Gbogbo alaye tí HSE bá ṣètò yoo wa ni ibamu si awọn ofin gbogbogboo ati ni pataki, ní Ilana Idaabobo Deta Gbogbogboo (GDPR) eyiti a gbekalẹ ní ọdun 2018. Ṣiṣeto deta rẹ yoo bá ofin mu laisi ojuṣaaju kankan. Fun idi pataki lati ṣakoso awọn abẹ́ rẹ́ - àjẹsára nikan ni a maa ṣètò rẹ̀ fun.

A ti lo ilana Àdínkù Deta (Data Minimisation). Eyi tumọ si pe awọn deta tí ó ṣe pataki lati ṣe idanimọ rẹ, ṣeto ìpàdé, ṣe akọsilẹ abẹ́rẹ́-àjẹsára rẹ ati ṣe amojuto awọn bó ṣe ṣiṣẹ sí lara rẹ ǹkan ni o maa wà ní akọsilẹ.

O ni awọn ẹtọ yii gẹgẹbi ẹniti o ni deta labẹ GDPR nipa awọn deta ararẹ tí wọn n ṣeto naa.

- Beere alaye lori deta rẹ ati bí o ṣe maa ráàyè lati wo o (eyiti a mọ sí 'ibeere wiwọle lati ọwọ ẹni tó ní deta'). Eyi n jẹ ki o lè gba ẹda deta ararẹ tí n bẹ lọwọ wa, tí o sì maa lè wò ó bi a ba n ṣeto ní ibamu pẹluofin.
- Beere fun atunṣe awọn deta ararẹ tí n bẹ lọwọ wa. Eyi n jẹ ki o lè sọ fun wa lati ṣe atunṣe awọn alaye tí kò péye tabi tí kò tọna nipa rẹ.
- Beere pé kí a pa deta nipa ara rẹ rẹ́ tabi kí a fà á yọ kuro lasiko tí kò bá si idi fun wa lati tun maa ṣeto lori rẹ mọ́. O tún ní ẹtọ lati sọ fun wa kí a pa deta nipa rẹ naa rẹ́, tabi kí a fà á yọ kuro lasiko tí o bá n lò ẹtọ rẹ lati tako lílò ó.
- Sọ pe o kò gbà kí a lò deta nipa ararẹ mọ́.

Alaye siwaju si i nbẹ ní **www.HSE.ie/eng/gdpr**

COVID-19 VACCINE
Public Health
Advice

Atẹjade lati ọdọ HSE **Ọjọ́ Kẹwàá Oṣù Kejì Ọ**dun 2021.

Rialtas na hÉireann
Government of Ireland